# IROHIN IMỌLẸ

IMOLE ORE AIYE TENI GROGBO LAWA

No 1,575 THURSDAY DECEMBER 2, 1965 (2D)

## Iyawo Oloye Ọshuntokun Sonu !

ESA-OKE:- Ninu irohin to de ile iṣẹ wa ni irọlẹ ọjọ Iṣẹgun ti iṣẹ ọgbọnjọ oṣu to kọja yi ni ati gbọ wipe awọn enia kan ji iyawo Minista Alamojuto eto ọkọ fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun iyaafin Ọshuntokun nigba ti o npadabọ lati iluọkọ rẹ ti iṣe Okemesi wa si Ibadan ni awọn enia kan ti iṣe awọn ẹgbẹ oselu lo kọlu ninu mọto ti o ngbe bọ lati ilu na.

Irohin awọn ọlọpa tun fi ye wa pe iṣẹlẹ na ṣẹlẹ nigbati iyaafin Oshuntokun nbọ ni ilu Ibadan lati Okemẹsi ti iṣe ilu ọkọ rẹ eyiti awọn enia na fi da mọto ayọkẹlẹ ti o ngbe bọ wa si Ibadan duro.

Irohin na tun fi ye wa pe gẹgẹbi mọto ayọkẹlẹ ti fẹ de Ẹsa-Oke ni awọn enia na ba da mọto iyaafin Oshuntokun duro ti nwọn si gbe e kuro ninu mọtọ na ati pe awọn enia na tun ba mọto ayọkẹlẹ na jẹ koja eyiti yio ṣe tun ṣe.

Ṣugbọn awọn ọlọpa fi ye wa wipe awọn ko ti mọ ibiti nwọn gbe iyaafin Oshuntokun na lọ titi di asiko ti a fi nkọ irohin na bayi.

WO OJU EWE KẸFA

### DOKITA OKPARA SỌ PE ;

# AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ DẸMO TA ỌFA SOKE, NWỌN YI ODO BORI !

## Olọpa Ati Ṣọja Lo Nsọ Ile Wọn

ENUGUN:- Gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati awọn ọkẹaimọye enia ti nwọn lọ woran ninu ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ na lo ya ẹnu silẹ ti nwọn ko si le pade ti gbogbo wọn si dake jẹẹjẹ nigbati Alakoso Ijọba Ipinle Ila Orun Naijiria ati olori ẹgbẹ Alakukọ Dọkita Michael Okpara nfi ye awọn ọmọ Ile Igbimọ na pe awọn enia kan gbimọ lati lefi ibo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria doju ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA) bolẹ ati pe awọn enia na ti nwọn fi ọna eru ṣe idibo na ti nwọn gbe are fun ẹniti o jẹbi nfi ọgbọn eru sọ pe ki ọlọpa ati awọn ṣọja da abo bo wọn lẹhinti nwọn ṣe iṣẹ ibi.

Dokita Michael Okpara nsọ eyi ninu Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ni ọjọ ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kini oṣu yi.

Oniwe irohin wa kan ti o wa ninu Ile Igbimọ Asọfin Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ran wa leti pe eyi ni yio jẹ ẹkarun ti Dokita Okpara yio sọrọ lori rogbodiyan to nṣelẹ lori abayọri idibo si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti nwọn ṣe idibo rẹ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi.

Siwaju si i Dokita M. I Okpara tun ṣe alaye pe ohunti o le mu ki eto alafia ati Ijọba rere le pada si Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bayi ni pe ki nwọn yọ Oloye Ṣammel Ladoke Akintọla kuro gẹgẹbi Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Dokita Okpara tun ṣe alaye pe on ko faramọ irohin kan to jade laipẹ yi pe ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun pe ki iṣe lati Ipinlẹ na bikoṣe wipe lati ẹhin -odi Ipinlẹ na lo ti nwa. Dokita M. I. Okpara tun ṣe ṣe alaye pe ọjọ to ti rẹ ni awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti njiya lati ọwọ Oloye S. L. Akintọla ati awọn Elẹgbẹ rẹ o ni gbogbo na ti su awọn enia na ati pe awọn enia na ko tun fẹ jiya odu marun miran lo nwon mu nja pe awon ko fẹ ki Oloye Akintola tun ṣe akoso awon.

Dokita M. I. Okpara tun ṣe alaye pa awon enia na tun sun kan ogiri ati pe ohunti oju won ti ri ṣẹhin ni Ipinlẹ na lowo Oloyei S. L Akintola nwon ko fẹ ki oju won tun ri ti odun marun miran lo mu won nja ati pe awon enia na ko si dibo won fun ẹgbẹ Dẹmo (NNDP) eleyi si jẹ ohunti o mu won nja jati fi han pe awon ko mo egbe Dẹmo ni Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria.



Aworan oke yi ni ti ile iṣẹ ti Ijọba Ibilẹ ti Mushin eyiti nwon dana sun ninu ose yi. Gbogbo ewon ohun elo ninu ile iṣẹ Ijọba ibilẹ na lo jona rau-rau ti ko si ohunti o ku silẹ ti ko jona.

Eleyi ni awon ohunti o nṣele lori abayori ibo si ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiri lori Ijoba eru ti nwon enia Ipinlẹ na sọ pe awon ko fẹ ni ipinlẹ na.

Dokita Okpara tun se alaye pe ireti ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA) lasiko idibo si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria ati pe ki nwọn si ko gbogbo awe ljo ko to wa ninu ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ na nitoripe ko si ẹniti o mọ ẹgbẹ Dẹmọ ni jakejado Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria.

Dokita Okpara tun ṣe alaye pe Alaga Igbimọ eto Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria ọgbẹni Ẹyo Esua ti fun ara rẹ so fun araiye gbọ wipe otitọ ni nwon fi ọna eru se eto ibo ti awon enia Ipinlẹ Iwọ orun di laipẹ yi ati pe gbogbo eto bi ibo na ti nlọ ni ko gba eto ofin ibo lọ rara ati pe ki ise on lo fa ọna bi awon ẹgbẹ Dẹmọ ti se fi ọna eru ṣe idibo na bikose wipe ẹgbẹ Dẹmọ lo se eto na fun ara won

Dokita Okpara tun se alaye pe bakanna ni asiko idibo si ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria ti ọdun to kọja eyiti awọn ẹgbẹ (NNA) fi ọna eru sọ pe awọn lo wọle atipe ẹgbẹ UPGA si gba lati ba wọn sisẹ pọ

Dokita Okpara tun se alaye pe nipa ọna ti ẹgbe Dẹmo gbe eto ibo na gba eyiti ise ona eru ati jibiti o ni ẹgbẹ UPGA lo tun bori ibo na o ni awon iwe irohn kan ti ise Daily Times Mornig Post ati Express eyiti o ti ku bayi kuna lati ko irohin otito nipa abayori ibo na jade

Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun tun ṣe alaye pe dipo ki awon iwe irohin na sọ otitọ, o ni nṣe ni nwọn ntan awọn enia ilẹ Naijiria jẹ nipa irohin eke to wa ninu awọn iwe irohin na.

Dokita Okparu ti o fi nkan bi wakati kan aqọ sọrọ ninu Ile Igbimọ Asofin na lori ibo Ipinlẹ Iwọ Orun tun ṣe alaye pe bi ko ba ṣe awọn iwe irohin kan ti iṣe iwe irohin Pilot, Nigerian Tribune, Nigerian Outlook, Irohin Imọlẹ ti nwọn gboju lati kọ awọn irohin otitọ jade fun awọn enia lati mọ bi nkan ti ṣe nlọ si ni Ipinlẹ na.

O ni bakannaa ni awọn iwe irohin lati ilẹ Okere

WO OJU EWE KẸFA

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## Latifu, Ẹ Ku Ewu Ọmọ

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba *mi* ni aye kekere yi lati ba Ọgbẹni Latifu Babalọla yọ ati lati ki ku ewu ti Iyawo rẹ Iyaafin Falilatu Babalọla ti o bimọ binrin jọjọlo kan fun laipẹyi.

Inu mi dun pupọ nigbati mo gbọ pe Ọgbẹni Latifu bimọ nitoripe mo mọ Ọgbẹni Babalọla bi ẹni mọ owo o si jẹ oniwa pẹlẹ ati ọmọluwabi enia paapa ogbokangi kan lo jẹ ni ile iṣẹ Itẹwe Modupẹ Press ti iṣe olutẹwe Irohin Imọlẹ

Lakotan mo ki Babalọla ku ewu Ọlọrun ko da ọmọ na si o ki o si ṣe ọmọ na ri ẹlẹmi gigun fun ẹnyin obi rẹ ṣugbọn ki nto pari ọrọ mi mo fẹ sọ fun Ọgbẹni Latifu Babalọla pe emi ko ti mu ọti ọmọ ti emi ngo si kan ọ lara ninu ile rẹ ni nomba 102A Ọduafa Street Eko laipẹyi ki o ma reti mi o

Emi ni
Ajẹloju Onile
Eko

## Mo Ki Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Dakun Gbajumọ olotu iwe Irohin imọlẹ maṣe alaiko gba mi ni aye diẹ yi la ti fi kan sara si awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Eko.

Mo ki gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹn fẹre ni ilu Eko, mo si ba nwọn yọ nipa Ibo ti w n ninu ibo Ijọba Ibilẹ Eko ni nwọn di kọja lo yi.



OLOYE AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Emi ti mo kowe yi jẹ ọkan ninu alailehin nwọn ti o si ni ifẹ Olori Ẹgbẹ na l'ọkan papa idisilẹ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, nigbati irohin de si eti gbọ wa pe ẹgbẹ na bori ninu ibo Ijọba Ibilẹ Eko ti nwọn di kọja lọ yi.

Mo yọ fun gbogbo ẹnyin ara ilu Eko, Oluwa yio wa pẹlu wa yio si sọ Baba L'Ayinka de wa ba wa layọ ati ara lile.

Emi ni
LATI WEST
IBADAN.

## E ku orire o

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati ki awọn enia to ngbe ni Ward H 1 titi de Ward H 6 nyin yiyan ti nwọn yan Ọgbẹni Ganiyu Olawale Dawudu gẹgẹbi Alaga Ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko ati paapa mo tun ba Alaga titun na yọ peki o ku orire fun ori aga ti Ijọba ibilẹ ilu Eko ti nwọn yan si gẹgẹbi Alaga.

A si dupẹ pupọ fun Olorun Ọba fun ipo ti Ọlọrun yan si gẹgẹbi eni akọkọ ti nwon yio yan ni Word H 2 gẹgẹbi Alaga ti Ijọba ibilẹ ilu Eko lati igbati nwon ti nṣe Ijọba ibilẹ ilu Eko bọ

Adura mi nipe ki Ọlọrun jẹki igba rẹ san gbogbo awa enia Ward H 1 titi de Ward H G ati paapa julọ awon enia ilu Eko ki Ọlọrun Ọba jẹki Alaga titun na fi ẹmi gigun lo aye rẹ na pe o.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹgba mi ọrọ yba ko ni sa nyin lẹṣẹ ajiude yio, ma jẹ fun nyin o.

Emi ni,
Azeez Shitu Ẹbẹdi
Eko

## Mo Ba Dawodu Yọ

Olotu, Jọwọ gba mi laye ranpẹ yi ninu gbajumọ iwe Irohin Imọlẹ alaka gbadun lati ki ọgbẹni Ganiyu Oluwale Dawodu ku orire ti alaga Ijọba ibilẹ Eko ti nwọn yan si

Mo ba ọgbẹni Dawodu yọ pupọ, o ku orire bi a ba ni ṣe ete leso asiwaju re re ni Dawodu iṣe, o si tọ si aye ti nwọn yan si yi nitori o fi gbogbo ara ati ẹmi rẹ ṣiṣẹ fun idagbasoke ilu Buba rẹ o si tun duro ti ẹgbẹ Afẹnifẹre nigba ipọnju ni Alakukọ bikita fun ohun to le tidi rẹ jade si Ọgbẹni Dawodu, asiko tirẹ yio tu wa lara lọmọde lagba onile ati alejo ni ilu Eko Oluwa yio si ma ṣe amọna rẹ ninu gbogbo idawọle rẹ.

Emi ni
Azeez Shitu Ebedi
EKO


# Kere o Kere o Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hantuhanu Egbogi LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamari olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọrọ sọya tati pe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanrẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku lara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogqo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ se enia nipa siso di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere sile mẹta abo (3/6) pere. Ber Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ n Ṣọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787
NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos
ATI NI ṢỌBU
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE IBADAN

## Angelina Super -- Rose
(O TI LỌ WA JU)

Eleyi ṣẹṣẹ jade ni ko si nita rara aṣẹṣẹ jade ikan a ko mọ ititi o lọ ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba lọkunrin ati lobinrin o tun wa fun irun didi ati kiko lowu o nmu irun ọkunrin papa ma dan ki o si jọlọ o ma fun ara ni ẹwa akotun awọ ara yio jẹ yọ jade perepere

Bi enia dudu ba loo yio ma dan gẹgẹbi jigi enia pupa agaga ṣe iyen ti wa tẹlẹ.

Tere sare wa tabi ki o kọwe fun tirẹ loni ki o lo tun ni "International Cosmetic Industries" 36 Ọmọwunmi Street, lẹhin kansulu Mushin Ẹ tọju ara ati irun nyin ẹ tọju pelu awuje ọmọ nyin owo poku ni 1/3 fun ẹyọ kan 15/- fun mejila wa fun alaye si.

# Ęgbę Dęmọ Wọ'lę Ni Ijębu

IJĘBU ODE:— Ninu irohin to de ọwọ wa lati ọwọ oniwe irohin ni ilu Ijębu-Ode fi ye wa pe ọgọrọ enia ti nwọn ti wa ninu ęgbę Dęmọ ni Ijębu-Ife, Ọwu, Ikeja, Imushin Iwaya, Imuweo, Itele, Ogọęrę, Imobi ati ęgbę gbe eti o ni ni a gbọ wipe awọn enia na ti binu kuro ninu ęgbę Dęmọ awọn si ti pada sinu ęgbę Afęnifęre.

Ninu awọn enia saraki saraki ti awọn pẹlu awọn enia to binu kuro ninu ęgbę Dęmọ ti awọn pada sinu ęgbę Afęnifęre ni awọn adajọ ti ile ejọ Ijọ ba bilę awọn Ajọju ni ile Igbinọ Ijębu ibilę ati ękun Ijębu awọn ijoye Paul Ọję made V O Kukọyi Yisa Dina, Andu Ękęrin, Lami na Erugbe ati awọn Ọgbę ni Kasali Olutolulęsę Saka Ogunkọya Nobu Ogunsọya Sunmọla Shegun Sanni Sędun Lasisi Jiga Alla Kamọni Oshikọya Isaac Shejo Bajo Moses Lawie nee K shimu Rabin Bu a mọ Andu Banjo Pius Ban jeko, Ailaru Taiwo, Sauni Aina ati awọn iyawo awọn enia ti o wa loke iwe yi ni nwọn ti binu li ęgbę Dęmọ silę ti awọn si ti pada si ęgbę Afęnifęre

Ninu iwe ti awọn enia na o kuro ninu ęgbę Dęmọ eyiti nwọn kọ si Ọgbęni A. F. Odulana ti nṣe Olori ęgbę Dęmọ ni iha Gusu Iję bu ni awọn enia na ti ṣe alaye pe awọn si ti mọ ati pe bi ti o da awọn loju pe ęgbę Dęmọ ko ni enia kankan Ijębu bikoṣe wipe awọn ęgbę n fę fi ọna eru ma ṣe eto akoso Ijọba ati pe awọn mọ daju pe ko si enia kankan to dibo fun ęgbę na wọle rara ati pe ọna jibiti ni nwọn gbe sọ pe awọn lo borilo ti awọn di ninu oṣu kewa ọdun yi

Awọn enia na tun sọ ninu iwe ti awọn kọ si Ọgbęni Odulana pe awọn si tun mọ daju bayi pe ęgbę Dęmọ (NNDP) ję ęgbę Oselu kan ti gbogbo enia ti kọ silę ati paapa julọ lasiko ibo

Awọn enia na sọ ninu ipari ọrọ wọn pe awọn si ti kuro ninu ęgbę Dęmọ ati pe awọn si ti pada sinu ęgbę Iłęsiwaju eyiti o de awọn loju pe ęgbę UPGA lo le ṣe eto akoso Ijọba Ipinlę Iwọ Orun eyiti alafia ilọsiwaju ati eyiti irokanba lę yio ti de ba gbogbo awọn enia Ipinlę na

# YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Ayọ ni fun ọ ni gbogbo ọjọ oni pẹlu ara bile ti ko si ohun kan lati damu rę

PISCES [Feb 21 - Mar 20] Tun gbogbo nkan ti o ti nṣe bęrę ni irin ọna ti awọn enia yio fi ma sọrọ rę yio dura fun ọ

ARIES (Mar 21 April 20) Maṣe fi ọwọle ohunti tun kan ti iwọ ko ṣeri ero ti nwọn ngba si ọ nipe ki a le fun Ọlọrun.

TAURUS (April 21 May 20) Aisan kekere kan yio ba ọ ję ṣugbọn alafia yio de ki o to to aṣalę

GEMINI (May 21 – July 21) Maṣe lọ fi owo fa ijogbọn wa ba ara rę jęki o di gbati ile ba ki o ma ba ṣina

CANCER (June 22 - July 22] O ni lati wa akoko, pataki lati fi wa iṣę ṣe loni iwọ yio si ri iṣe ṣe.

LEO (July 23 - Aug 22) Tętętęlę gbogbo nkan dun loni ko ojọ loju ṣugbọn maṣe ṣe iru rę loni

VIRGO (Aug 23 - Sept 2 ) Iwọ yio ri oju rere orę re gb tobę ti iwọ ko ni gba gbe ori na ti o ṣe fun lailai.

LIBRA (Sept 24 - Oct 33) obirin gbajumọ kan yio a s, ọ fifę ara ẹni bi o ba mura ọrọ na yio di ayuwo rę.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 2 ) Ino rere rę si awọn enia yio u ọrọ ire ati owo wa fun ọ,

SAGITTARIUS Nov 23 Dec 21 Maṣe ba ęnikan sọrọ ... ki awọn ma ba ṣe ofofo pe iri re pọju

CAPRICORN (Dec 22 – Jan 21) Maṣe ṣe ohun koto ni ayeju ki a ma ba pe ọ ni eleke,

# EGBOGI JEDIJEDI

BERE FUN EGBOGI

"CYCLEVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jędijędi rę gbe wa lara rę o si nyọ ọ lenu nigba gbogbo. Ibę ni a npe ni "omusu" ti bi iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsę. Arun Jędijędi ję ikan ninu aarodi ti o buru ni pataki fun Okunrin ti o si ṣagbara lati ṣe iwosan rę palapata.

Ọpọ ọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri odę nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rę ṣugbọn boya la le ri mewa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara. Awọn ęlomiran lere wipeboya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo kę eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni. pa bę awọn o bọ lowo rę palapata

Ṣugbọn awa ko to bę rara: Lenin odun ale iyonu rę yio si tun ma bęrę baka na, Orisirisi Jędijędi ni o wa ękini ti o bęrę ọipa aiko ma ṣe igbonse dede tabi lojojumo ęlomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumo tabi gigun keke ylogere (Basik-lu) pupo ęlomiran ewe nipa iji Ṣuga tabi onirere ohun adidun pupọ ju. Jędijędi orisirisi ni o wa ewo ni tirę? Bi o ba nyọ jade ninu omusu ta i ti o ba nmu wa lęhin igbonsę tabi to ba i nyọ ti o ba ṣe igbonsę tan ni, tabi ti o n o ninu musu ni eyikeyi ti o bara bęrę egboki "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani fere wa idi rę ko ki o si dawọ orisi męta ni o da u wipe iwo yio bọ lowo Je i p tapata alafia y'o de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi si igboro ni Naijiria Bere re ni:—

Waterloo Medecine Store

8, Palm Church Street Lagos,
Phone 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

# O Ti De Jaburata

Eyi ni lati kede fun awọnOnibara wa pe. Iwe itumo Ala. Iṣę Wiwo, ojọ ibi Omode lati Oogun Ajebidan alapapo wa nilę fun tita nisisiyi, tete wa ra irę loni ki o to tan.

Asi tun ṣęsę ṣe Iwe itumo Ala miran ati iwe Joseph Alala

Irohin ko to afojuba 3/6d pere ni ęyọ kan, mejila tabi dosin rę ję 30/-



Ọgbęni J. O. Shoyinka

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9. Iyala Street
Mushin.

Asi nię awọn ti yio ma ba wa ta awọn iwe wa na

Tete wa si ọdọ Olotu

POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin

